## Akiyesi Pataki

A fiwe yi şe ikede si awọn Aşoju iwe irohin Eleti Ọfẹ kakiri agbaiye wipe enikẹni ti ko ba fi owo ti o ti jẹ ranşe si wa ao pe lẹjọ, ako si ni fi iwe irohin ranşẹ si enibẹ mọ.

# ELETI ỌFẸ

A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJO

## Sayan Oro

Ewurẹ wọ alapata, bi ki o ku: Awodi wọ Igbin korọ, Kini ẹiyẹ oko yio fi Igbin se ? Ori l'o nişe eda l'a yanmọ

VOL. XI No. 653. LAGOS, SATURDAY, DECEMBER 12, — DECEMBER 18, 1959. KỌBỌ MEJI (2d)

# Jesu Agege Riran Si Egbe Afenifere (A. G.)

AGEGE. Agbanyanu ni irohin kan ti a ri gbọ lati ọdọ Woli awọn Aladura kan, ti okiki rẹ gbojikan kakiri agbaiye ti nwọn npe ni Jesu Agege, nipa ibo ti ao di loni kakiri ilẹ Nigeria wipe :

Bi mo ti wa lori ekun mi, ninu adura mi si Ọlọrun ni iwọn agogo meji oru mo ri imọlẹ kan yọ lati apa Ila-orun wa, mo si ri ọkunrin kan alaşọ adura o si ti inu imọlẹ na jade o ni iyẹ ni apa rẹ mejeji ti o si dabi ti ẹiyẹ Idi.

Oju rẹ nkọ mana-mana o duro ni waju mi, o si pe mi ni orukọ ti mo njẹ bayi pe "Samuel Lakko"! Nihin ni ara mi bẹrẹ si gbọn, o si nwariri, Angeli ni yi tabi kini ? nitoripe o jọ Mọlaika loju mi.,

O wi fun mi pe, ma bẹru, iranşẹ bi iwọ lemi nşe. Lọ nisisiyi si ọdọ ẹgbẹ Afẹnifẹrẹ ki o si sọ asọtẹlẹ fun wọn bayi pe, ninu gbogbo ibo ti ao di loni yi, iwọn yi ni iye ijoko ti ẹgbẹ Afẹnifẹrẹ yio ko ninu gbogbo ibo na:-

Ẹgbẹ A.G yio ko 90 nilu awọn Hausa-Ariwa, 50 ni Iwọ-orun, 30 ni Ila-orun ati 2 nilu Eko.

Nje nisisiyi, ẹ ma yọ, ẹnyin ẹgbẹ Afẹnifẹrẹ, Ọpẹ l'oni ayo, Igi owo!.


## THE NATIONAL BANK Of Nigeria Limited

Incorporated ni Nigeria in 1938
Paid up Capital £1,130,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria
HEAD OFFICE
37, MARINA, LAGOS NIGERIA
22 Branches Throughout Nigeria including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE, OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA, ILARO, BENIN-CITY, WARRI, SAPELE ABA, KANO, ZARIA, JOS

LONDON OFFICE
1 THROGMORTON AVENUE. E.C. 2.
Manager: F. O. Tyrrell.

Telephone: London Wall 4303 — Cables & Telegrams Natbaniger London.
Head Office Representatives in London
E. Akinwunmi Doherty.
CORRESPONDENTS
NEW YORK, PARIS HAMBURG.


## Akotan Oro Fun Awon Adibo



Ẹniti a nwo aworan rẹ yi n Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ti işe Akonijẹ egbẹ Afẹnifẹrẹ ati Olotu ijọba Iwọ-Orun ti Jesu Agege riran si ẹgbẹ re wipe yio bori ninu ibo ti a o di loni.

On l'okesi awọn adibo ilẹ Nigeria wipe, ki nwọn ranti işẹ rere ti ẹgbẹ Afẹnifẹrẹ (A G) ti şe si ipinlẹ Iwọ-Orun ti nwọn fi gbe ijọba le wọn lọwọ l'ẹmeji lẹrawọn.

Ki Ọlọrun tọ wa s'ọna rere.

### OLOYE MODILẸ W'AJA

Oloye Mọmọ Salami Batula, ti o jẹ ọkan pataki ninu ẹgbẹ awọn ijoye ibile Ọgalade ninu Ijoye ilu Eko ni a gbọ wipe, o Şalaisi ninu ile rẹ ni Idita nigbati o di ẹni ọdun mẹtadilọgọta nile aiye.

A gbọ wipe Musulumi paapa ni Oloye yi siwaju ki o to jẹ oye ko si fi iran silẹ. Nigba aiye re on ni akowe fun ọba ati ijoye, o joye na ni ọdun 1950 ki o to wa goke alọ ni opin odun kesan.

O ku o fi iyawo rẹ ati ọmọ meji silẹ, ni ọjọ Monday 7th oşu December 1959, nwon si sinku rẹ ni agogo merin irole ojo Tuesday.

## Ko Si Eniti Ofin Ilu Mi Ko Le Lo.

ILỌRIN. Agbọ irohin wipe, ọmọkunrin agbalagba kan ti nwon npe ni Gidado Iyanda ti o to ọmọ adọta ọdun ni ọjọ ori rẹ, ni ọwọ awon ọlọpa tẹ, ti nwon fi sun ẹsun atẹnabọle wipe o tẹ ina bọ ile Salumọnu Ajape ni ojọ Jimo 27th oşu November 1959, ni abule Odonigi, o si jo ile na rawu-rawu.

Nwon şiro dukia ti o jona sinu ile na, o to ponun mẹrinlelogoji ati şile meji abọ (£44-2-6)

Nigbati nwon mu ọdaran na dewaju ọba Ilorin, Malam Sulu Gambari, Ọdaran na, Gidado Iyanda sọ pe on ko jẹbi, bẹni on ko fẹ ki a şe ẹjọ on niwaju ọba Ilọrin. Şugbon ọba kọ-o dahun pe, bo fẹ bi o jẹ Oniгbagbọ, tabi Imale tabi Abọgibọpẹ, ko si ẹniti ofin ilu mi ko le lo ni won igbati ẹni bẹ ba şi wa nilu mi nibin.

Nwon şe ẹjọ na ọba si da Gidado Iyanda lẹbi atẹnabọle nwon ju si ẹwọn ọdun meje.

# Enia Dudu Onise Iwe Irohin



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Ogbẹni Alade Odunewu ti o nṣe Olotu iwe irohin (Daily Service) ni a koko ti o lọ silu Oyinbo fun ilọsiwaju ẹkọ ninu iṣe iwe irohin. Ibiti o ti kọ iṣẹ na ni abẹ Oniwe irohin kan ti a npe ni "Worthing Herald" nilu Oyinbo.

## ỌLỌPA MU AWỌN TO DA'KO EWE TABA IGBO

ABA. Irohin kan wa wipe, larin ilu Aba, ni ọlọpa ti ragabu awọn enia meji ti orukọ wọn njẹ,. Michael Ojiri, ati Godwin Onwesiyigbe fun ẹsun wipe, o ṣe ọgbin ohun ti o lodi si ofin.

Ẹsun ti nwọn fi sun awọn ọdaran mejeji na ni wipe nwọn da oko, nwọn si ṣe ọgbin ohun ti o lodi si ofin ohun ti nwọn ṣe ọgbin rẹ na ni iru ewe taba kan ti nwọn npe ni Igbo, eyiti ijọba ti ṣe ofin le lori, wipe nwọn ko gbọdọ ri ewe taba na lọwọ ẹnikan. Ẹnikẹni ti o ba mu ewe taba Igbo na tabi nwọn ri lọwọ enia, oluwarẹ di arufin.

Awọn mejeji mbẹ ni ikawọ awọn 'ọlọpa, ẹjọ na si mbẹ ni kotu.

## IJỌGBỌN ILẸ YAWẸNDẸ NI KAMARU NPELEKẸ

KAMARU. A gbọ irohin wipe, awọn ẹya kan ninu awọn Yawẹndẹ ti a npe ni Bamilake pade awọn Imale oniṣowo kan lọna ninu igbo kan ni agbegbe ilẹ Yawẹndẹ ni Kamaru. A gbọ wipe awọn Imale oniṣowo na kọ lati gbe ẹru wọn silẹ fun awọn Bamilake na, ibẹ ni ija si ti bẹrẹ. Ẹni mẹta lo ku patapata iwọn ogun enia si fi ara gbogbẹ ti nwọn ko le dide rara.

Imale kan ti ada ba ni ori lo ku, awọn meji ninu ẹya Bamilake lo ku patapata. Nigbati ọrọ yi de etigbọ aṣiwaju ilẹ na Ahmdou Ahijoh kia lẹsẹ kanna, on pẹlu Olori awọn Amofin ilu na gbe mọto lọ sibiti [ija na ti ṣẹlẹ. Oga ọlọpa kan tẹle wọn lẹhin, nwọn lọ ba awọn ara abule to mbẹ nitosi ibiti ija na ti ṣẹlẹ wipe

(Wo yoku loju ewe keje)

## Awon Omo Akeko Nilu Oyinbo



Ẹniti o duro ni arin meji awon enia meta ti o duro nwọnyi ni Ọgbẹni J. B. Ọdẹwale, ọkan ninu awọn ọmọ akẹkọ ti o lọ silu Oyinbo lati kọ iṣẹ, Ẹniti o duro ti ni ẹgbẹ ọtun ni Ọgbẹni S. A Cookey ara agbegbe Ila-Orun ilẹ Nigeria.

## GESI YIO WA BA WA ṢERE AYỌ FUN OMINIRA

LONDON. A ri irohin kan gbọ wipe ninu awọn ere idaraya ti ao nṣe nilẹ Nigeria fun ti ayọ ominira ti gba ni ọdun 1960, awọn Gesi ti ranṣẹ wa wipe awọn yio ko awọn oṣere wọn lati wa ba wa ta pero diẹ.

Nigeria yio gba alejo rẹpẹtẹ ninu awọn ti a gbọ wipe o tuu mbọ bẹ ni awọn Amerika, Jamani, Ghana, Gini, (Guinea) Togoland ati Dahomi ogunlọgọ ni awọn ẹya miran ti o mbọ wa ba wa yọ ayọ na.

A tilẹ gbọ wipe, Oyinbo ti o ṣe ọṣọ igboro London ni aṣiko ti ọba obinrin lẹ gba ade ni nwọn ranṣẹ si pe ki o wa ṣe ọṣọ ilu Eko lasiko ominira ilẹ wa. Ki Ọlọrun jẹki ọjọ na ṣe oju ẹmi gbogbo wa Amin.


Kere o!

A ni oriṣiriṣi ogun German to ṣẹṣẹ de, fun onirunu aisan tọkunrin tobinrin. Tete wa ra tirẹ ki o to tan.

J. A. AJAO BROTHERS

MEDICINE STORES

7, Egerton Road Lagos

No 187

# FEDERAL ELECTIONS 1959.

## USE OF VEHICLES ON POLLING DAY

Candidates and political parties are remined that no vehicle bearing a party symbol may approach within 200 yards of a polling station (Regulation 114(h).

No other special restrictions have been placed on the movement of vehicles on polling day either by the Electoral Commission (using their powers under Regulation 142) or by the Police

**R. E. WRAITH**

Chairman, Electo ral Commission

## New Freight Rates To Ibadan.

YOU MAY NOW SEND YOUR GOODS BY FREIGHT TRAIN TO IBADAN FROM APAPA QUAY, APAPA LOCAL STATION AND LAGOS TERMINUS AT THE FOLLOWING SPECIALLY CHEAP RATES:

| | RATE PER TON |
|---|---|
| CEMENT .... — | 15/- |
| IRON SHEETS — | 20/- |
| ALL OTHER GOOD (Above Class 4 of the Railway Classification) | 22/ |

THERE ARE NO WEIGHT LIMITATIONS

The NIGERIAN RAILWAY CORPORATION will carry all your Loads however Large or Small

SEE HOW THESE NEW RATES COMPARE WITH THE OLD RATES :-

| COMMODITY | RATE PER TON TO IBADAN From Apapa, Lagos & Iganmu | |
|---|---|---|
| | OLD RATE | NEW RATE |
| Sugar | 38s | 22s |
| Beer, Ale and Stout | 38s | 22s |
| Piecegoods: | | |
| Manufactured | 55s | 22s |
| Unmanufactured | 42s | 22s |
| Petrol | 57s | 22s |
| Hardware ) Groceries ) Confectionery ) | 42s | 22s |
| Timber | 29s | 22s |
| Cement | 23s | 15s |
| Iron Sheets | 29s | 20s |
| All other traffic above Class 4. ) | 23s to 63s | 22s |

# Jamba Moto Se Aburo Ernest Ikoli



SURULERE. A gbo irohin wipe Edward Ikoli ti o je abure fun Ogbeni Ernest Ikoli ni moto Oyinbo kan sesi lo kolu ni Surulere, o si pa lọ orun Alakoji are mabọ.

Bi iku na tisẹ sele ni wipe, jẹjẹ ni Edward ngun keke re kojalẹ ni Western Ave, ki owo oyinbo na to ju, ti o si lo kolu ọkunrin na. Awọn olopa ti gbe oku re lo si ile alaisan fun ayewe lati mọ kini ohun ti o se iku pa ọkunrin na.

Eniti a nwo ninu aworan yi ni Ogbeni Ernest I koli eni ti a gbe wipe o je egbon fun Ologbe na. Ki Olọrun so wa ki a mase rin lojo ti ebi npa ona.

## Itan Osuogbo

(APA 3)

(Lati ọwọ Opitan)

Ọtẹ kan sẹlẹ larin Awo Osuogbo, eyiti o fọ awo na titi di oni yi. Bi ọtẹ na ti sẹlẹ niyi: Ikusigbagbe ni iku na pataki ti o npa won ninu Awo Osuogbo o jẹ olagba, isẹ egba ti nwon fi npa ede lo nse, eyi si ni isẹ ti gbogbo enia mọ pelu rẹ. Awon opitan so pe Ikusigbagbe a ma pe pupọ ni isalẹ omi, nigbati egba rẹ ba kọ aisalẹ omi, tabi nigbati ngbati nwon ba be e lati wa isan fun won.

Isẹ nwonyi ni ọpọ awon omo awo Osuogbo mọ ti ọkunrin na nse, gbogbo enia ko si mọ wipe ọmọ Awo ni isẹ. Larin awon olori ati ijoye inu egbẹ na nwon mọ pe Ikusigbagbe ni igbakeji Oluwo awo Osuogbo, iyẹn ni wipe, bi Oluwo ba ku Ikusigbagba ni Oye na kan.

Awon ti enu rẹ tolẹ ninu ẹgbẹ bẹre si ku, tobẹ ti o fi wa ku awon ti enu won ko tanlẹ. Nigbati o se, Oluwo ku, nibiti awon ọmọ Awo gbe ajiroro ni Ikusigbagbe ba wọle to won. Ni akoko, nwon le pada, sugbon o fi agbara wo Iledi lo ba won. Awon ti o mo yesi jojo sugbon awon ti ko mọ o nlẹ le jade, o so fun won pe, on ni Apena ẹgbẹ na. Iru Awo bayi ko sa le wa ko ma ni Apena bi nwon ba si mọ Apena Awo Osuogbo kan nileyi, ki nwon jẹki on mọ. Bi Oluwo ba si ku Apena ni oye kan, gẹgẹbi Awo na.

Sugbon Asipa ẹgbẹ na mọ pe Ikusigbagbe ni oye Oluwo kan, ko da si ọrọ na. bi o si ti je wipe, o moye nipa ẹgbẹ yi ti o jẹ ọkan ninu imulẹ, ko sọ si ọrọ na. nitoripe on ni nwọn ngbero lati fi joye Oluwo.

(Wo yoku loju ewe karun)

## ẸGBẸ MAJẸOBAJẸ KO GBA KI FARANSE DAN ẸTU OLORO WO.

NEWYORK. Ninu ipade ẹgbẹ Majẹobajẹ (U. N.) ti nwon se lẹ laipẹ yi, ninu eyiti Ogbeni Gesi kan ti nwọn npe ni Ormsby-gore tako awọn Faranse lati fi han wipe yinyin ẹtu oloro na ko le mu ire kan wa sile aiye.

Ogbeni Ormsby-gore fi han igbimọ na iru ewu ti o wa bi nwọn ba yin ẹtu na. nigbẹhin, ẹgbẹ Majẹobajẹ fi aṣẹ si wipe ko to ki Faranse yin ẹtu oloro na nitori alafia awọn enia.

Igbimọ so pe ki nwon pase wipe Faranse ko gbọdọ yin ẹtu na mọ. Awọn orilẹ-ede mejilelogun parapọ ti nwọn gbe ọrọ ẹtu na lọ si ọdọ ẹgbẹ Majẹobajẹ. Pẹlu - pelu awọn Amẹrika ati Gẹsi ti o jẹ ọrẹ timọ-timọ fun Faranse lọwọ ninu wipe ki Faranse ma yin ẹtu na mọ.

# ELETI-OFE

A NIU-WON KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS   CABLES & TELEGRAM
S. Kopoko Street, Lagos   "ELETI - OFE LAGOS"
P. O Box 467   Phone 23370

VOL XL NO 653 SATURDAY DEC 12 - DEC 18., 1959


## Oni Lojo Pe

Owe Yoruba kan l'o sọ bayi pe "Pipẹ ti'l egungun odun ko ju itadogun lẹ, ọmọ Alagbaa yio ra akara mu'kọ". Ko si bi ọjọ kan tilẹ pẹ to kio ma ku ọla, ọjọ na pe loni, ọjọ ti a ti npokiki re fun ẹnyin ọkawe wa, ọjọ idibo yan awọn enia si igbimọ ijọba Apapọṣe, awọn ti o enia ti yio mu opo ijọba gbogbo-gbo ilẹ Nigeria dani, ti yio si mu Ominira ilẹ Nigeria wọle.

Ani, ọjọ ti a ti nkigbe fun olukuluku ẹnyin enia wa ati ẹnyin ọkawe wa lati pe Aro ati Ọdọfin inu wa wipe kia ronu arojinlẹ ki a maṣe ṣe aṣiṣe lọ dibo wa fun ẹgbẹ ti yio fe'hin wa jalẹ, tabi ẹgbẹ ti ko ni ọgbọn ati lakaye ti o le fi ṣe eto ipinlẹ agbegbe ilu rẹ nikan, bi ipinlẹ Ila-Orun tabi ti Ariwa, Oke Ọya, ti o jẹ wipe "Adiẹ ba l'okun, ara ko rọ okun ara ko rọ adiẹ" ni ọrọ won nje fun ijọba won ati awọn enia rẹ.

Nje loni ti ọjọ na pe yi, a tun fi wosika wa yi ṣe nyin ni iranti wipe ki ẹ lọ tara si ile idibo ki ẹ si dibo yin fun ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group).

Edibo fun Ọpe, igi Owo!

# Electricity Corporation Of Nigeria

## INVITATION TO TENDER

### METERS

Tenders are invited from responsible factors for the supply, c. i. f. to Lagos, of 5,400 No. - Single phase, house service pattern, 25 Amp Meters with fully insulated cases and cyclometer dials suitable for use in the tropics on a 230 Volts 50 cps System, to be delivered regularly in batches of 300 per month.

On payment of a deposite of £5, tender documents comprising tender and specification of the contract may be obtained from the undersigned.

Tenders must state when the first batch of meters will be delivered in Lagos and the method of packing must be described.

Each tender must be enclosed in a sealed envelope marked "Confidential-Tender for Supply of Meters" and must be received at the Office of The Secretary, Electricity Corporation of Nigeria, Electricity Headquarters, 13 Broad Street, Private Mail Bag 2030, Lagos, not later than noon on Wednesday 20th January, 1960, and should be valid until at least 10th March 1960. Tenders received in any other manner will not be considered.

The Electricity Corporation of Nigeria does not undertake to accept the lowest or any tender.

Further information concerning this contract may be obtained on application to the Chief Electrical Engineer at this Headquarters.

C. K. O. Adenaike
Acting Secretary To The Corporation




AVAILABLE AT:-
A[illegible]SHILE BROTHERS
5, BALOGUN STREET WEST.
P.O.BOX 599. LAGOS.



OMORELA
Is the ever-ready way to get rapid relief from
Cough, Cold, Fever and all Children ailments.
This is a well tried remedy
a Chemist Product.



Commercial Medicine STORES
LAGOS & IBADAN.

## EBUN ILERA



Ara-lile, agbara ati okun-inu ni iṣura ti o koja idiyele, awọn ẹbun ẹda ti o dara julọ ni. Ko si onjẹ miran ti o nfun ni l'okun-ilera atata bi Ovaltine, ohun ti a fi peelo rẹ ni onjẹ atẹjẹṣẹ ati eyi ti o nfun ara ni okun. Mimu Ovaltine lojojumọ ni ọna to dara julọ ti o si tọrun julọ lati fun ni ni ọpọlọpọ ilera ti o dara tẹlẹ, lati ri i daju pe a ni okun lojojumọ ati idẹra, orun asunwọra. Ẹgbẹgbẹrun awọn ọlọmọde ni nwọn mọ anfani atata ti Ovaltine ni, onjẹ olomi ti o dara julọ





## Itan Osuogbo

(APA 3)

(O bere loju ewe keta)

Ijoye Asipa Aseo Osuogbo si, iọọ rẹ li si nso ni lati ma hun ago adiẹ, apere ati lati ma hun ẹgba ti nwọn fi npa ede, pataki iṣẹ rẹ ni lati ma wa ṣanrio ati isan, ko si le pẹ tobẹ nisale omi.

Ọrọ yi di ibinu ninu ilodi saṣawẹre so wipe nigba pupo ni awọn nṣe igbimọ ti awọn ko nri Sigbagbe awon ko tile ri apẹrẹ ọmọ Awọ lara rẹ, awon ko si mọ eni kan pe, en ni Apena ẹgbẹ Aseo Oṣuogbo,

(Koni pari)

## MO JA L'OLE NITORIPE O PE MI L'OLE

KADUNA. Okunrin Ọgigoje kan ti oruko rẹ nje Iworu Kwoi ni awon olopa ramu fun ẹsun wipe o ja ole. Ijo ti awon olopa en ni pe ni adugbo kan ti nwon npe ni Fodun Nwada nibiti obinrin kan gbe ntaja ni Kwoi gbe ti lọ ji okababa.

Alikali bere lowo Imoru Kwoi wipe ki lo tun sun o de ibi oka baba latul, nigbati iwo ko nṣe obinrin.?

Imoru Kwoi dahun wipe, ki adajo se gafara fun on, tele-tele, on ko nṣe ole, sugbon on ko ba obinrin na loro kan papọ sugbọ bi o ba ṣa ti ri en ni yio ma pe on ni ole, nigbati oko ja ni ole ri. Eyi nidi rẹ ti mo fi jẹwọ ole fun u.

## OLOYE ODẸBIYI JOYE APESIN NILU GBOGILA

IGBOGILA. Oloye J. A. O. Ọdẹbiyi ọkan ninu awọn Minister agbegbe Iwọ-orun ti o nṣe itọju owo agbegbe na, ni awọn enia fi jẹ oye Apesin ilu Igbogila ni agbegbe Ilaro.

Awọn enia ti o wa nibi ifinjoye na to edẹgbaji enia. Oloye na sọ fun wọn pe, ifẹ ina on ni lati mu ilọsiwaju wa si Igbogila, ki owo ati owo si ma gberu nile na.

O sọ fun won nipa ofin awọn ijoye ni agbegbe ilẹ Egbado. O si ṣe kilọkilọ fun awọn enia pe ki nwọn tẹriba fun ofin, ati ijoye ti o ba ju wọn lọ. Nitoripe aimọkan, ope ati arun je ọta buruku fun ọmọ enia.

Iru iwa bayi ni ijọba ko fẹ ti awọn si ntiraka lati parun. O kọ won ki nwọn maṣe dabi iran alagidi, iran ọlọtẹ tabi ẹniti ko ba Ọlọrun duro ṣinṣin.


MA KA

IWE IROHIN

ELETI-OFE

LỌSỌSẸ

O KUN FUN

IROHIN ALADUN

# Itan Ikoko Ati Agilinti

Amotekun ti orungbẹ ti ngbẹ ni, eyi ko ṣoro lati kọ oko orin ti Ikoko sọ fun bati kọ, o mu omi ẹrun o si rin wọ inu igbo lọ. Nigbati o ṣe, agbọnrin wa lati mu omi, lẹhinna Ehoro lẹhin eyi Imado gbogbo wọn ni Ikoko sọ bakanna fun, ko si si ẹniti o ro pe o yẹ fun on lati duro ba Ikoko jiyan ṣugbọn olukulu wọn ko orin na, o mu omi wọn si mba ona ti nwọn lọ ninu igbo.

Inu Ikoko na dun pupọ, l'alalẹ li o ma njoko lori itẹ rẹ ti gbogbo awọn ẹran ti o ba wa si eti odo si ma ntẹriba fun u. Ani Kiniun olori ẹba ẹranko tilẹ nwa ori fun Ikoko pẹlu bi ọla rẹ ti to ni o ko orin o si ba tirẹ lọ.

Li ọjọ kan ni ipari ọgbẹlẹ nigbati omi ngbe lọ ti awon ẹsinsin si nda awọn enia lamu Agiliti bọlọjọ kan jade lati inu igbo wa. O joko lati simi o si na iru gigun rẹ silẹ li ẹhin rẹ. Alangba nla ni Agilinti iṣe o si tobi to apapọ ọgọrun alangba O yoro ẹhin rẹ re, gbogbo enia li o si mọ ọ fun oye rẹ ati ahọn rẹ ti o muna. Erin ti o tilẹ gbọn julọ ninu gbogbo awọn ẹranko igbẹ ko jẹ ba Agilinti jiyan nitoriti o mọ pe agilinti yio da on ninu ijakadi.

Agilinti, ti o fẹ soke ti o si nmi hele-hele bẹrẹ si irin hẹbẹhẹbẹ lọ si eti odo na, o dabi ọmọ Oni. O ti imu rẹ bọ omi lati mu omi. Ṣugbọn Ikoko ko si i pẹ.

"Duro na iwọ ko gbọdọ da ẹ kan mi titi iwọ yio fi kọ orin yi, o ni lati kọ ọ bayi pe.
Fadaka ni Pepele re.
Wura lo fi bọ ọ
Ohun Ọṣọ wa leti rẹ,
Dajudaju Oni Ọba ni yi".

# Obinrin Kan Fe Lu Aboyun Pa

IBADAN. Obinrin aboyun kan ti o ṣẹṣẹ loyun o to ọmọ ọdun mejilelogun o nṣiṣẹ ni ibẹ Nigerian Tobacco Company, ni a gbọ wipe, obinrin ẹlẹgbẹ rẹ kan, lu ni ilakulu tobẹ ti o fẹrẹ ṣe aboyun na leṣe.

Adajọ bere lọwọ rẹ pe ẹṣẹ ti o fi lu obinrin na bẹ nigbati o ri iru ipo ẹlẹge ti aboyun na wa? O dahun, o sọ fun adajọ wipe, o ti mọ wipe emi ko bimọ ri ṣugbọn bi o ba ti ri mi ni yio ma fi oyun rẹ yangan si mi, nigbati ara mi ko le gba mọ ni mo ṣe lu ki akuku fọ gbogbo re loju.

Nigbana ni adajọ ba a wi, o si fi ẹjọ na fa a leti wipe ki o ma ṣe bẹ mọ. O ni ki obinrin na lọ san pọnun meje ṣile meje bi ko ba si ri san ki o lọ gbẹwa oṣu kan.

ILE IGBEBI NI IPINLE IWO ORUN



[illegible] Ipinlẹ Iwọ Ọrun lati ọdun diẹ sẹhin ni kiko Ile Igbebi [illegible]

[illegible] yẹ ki nwọn to bi'mọ, atipe bi ọjọ ba pe [illegible]

[illegible] Ile Iwosan Iyaba mẹdogbọn to wa ni Ipinlẹ yi [illegible] Alaṣẹ Ilulẹ kọọkọ ki nwọn le kọ iraṣẹ ile bẹ.

[illegible] fun awọn Alaṣẹ Ibilẹ lati [illegible] ni Ipinlẹ Iwọ Ọrun loni.

[illegible]

E MA KA
IWE IROHIN
ELETI-OFE
LỌSỌSẸ
O KUN FUN
IROHIN ALADUN





# LAGOS RACE CLUB

## Christmas Meeting

**Saturdays 19th & 26th Dec. 1959. Fridays 1st,**
**Saturdays 2nd & 9th January, 1960.**

Racing Starts at 2. 30 p. m. on the first day of the meeting, and at 2. 45 p. m. on the subsequent days

DECLARATION

To be made at the Secretary's Office between the hours of 5 p. m. and 6 p. m. on Fridays 18th, 25th, Thursday 31st December, 1959 and Friday 8th January, 1960.

ADMISSION TICKETS (ADVANCE PURCHASE)

ADMISSION TICKETS for the Meeting can be purchased in advance at the Secretary's office in the Paddock between the hours of 5 and 6 p. m. on the day preceding each day of the Meeting.

ADMISSION 5/- per day
including Entertainment Tax.

CHILDREN

No children under the age of 14 years will be permitted to enter the Members Enclosure.


*Always ask for*
**'DE FACTO'**
*the bread with the appetising flavour*


## ADAJO FA IWE IJO SATIDE-SUNDAY YA.

ABA. A gbo irohin wipe Ijo Satide-Sunday (Seventh day Adventist) po pupo ndu Aba, awon si le mo bi enu won ti tole si. Nitorina awon kowe si Ogbeni R. E. Wraith wipe ojo 12th osu December 1959 je ojo idibo nla ti gbogbo ara ile Nigeria ni eto si. Pelupelu ojo na bo si ojo isimi ti awon (Saturday) nitori eyiti awon ko gbodo se isekise kan. Awon fe so fun Olotu idibo wipe nilu Aba ni kan ijo won po to'oke kan enia (20,000) ti awon ni lati dibo.

Gegebi ojo idibo na si ti bo bo si ojo Saturday, inu won yio dun bi Ogbeni Wraith ba le yi ojo idibo ko si ojo Friday 11th osu December 1959 Oyinbo olotu idibo na dahun pe Ijoba ti da ojo idibo ko si le se yipada mo. Ijo na so wipe kini nje pe ko le se yi pada? awon yio yi i.

Ni Pastor Dike ati Bishop Tikili ba se iwe ebe loruko Ijo Satide-Sunday fi ranse si Adajo ni kotu wipe, bi o ti je pe Ijo yi lopoju nilu Aba, eriwo lo je fun awon lati se iru nkan be lojo Satide ti o je ojo isimi won. Nitorina ki adajo ba won ye ojo idibo na kuro ni ojo Saturday si ojo jimo.

(Koiti par i)

## IJONGBON ILE YA-WENDE NI KAMARU

O bere loju ewe keji

**ki awon se ara giri ki awon mu suru, awon olopa ti bere si lepa awon apanis na lo siwaju.**

**Awon to lo sibiti ija na gbe ti sele so wipe, bi o ba je wipe eyiti awon fi oju ri yen ni eyini ti kuro ni ija sue, sue, o ti di ogun jija gan.**

## ORIKI BAMWO

Bamwo de, alajala omode agbomola bi orisa, akokoluko ogun ti ndamo l'ekun igbona, atata ogun ti npa otutu re warawara a je bi idan, a gba bi etu ibon. O s'abiku di ikugbagbe, o s'omo ti nhebin l'ore, Iko ri i sa, Iba ko l'ona tagiri, aiperi ri d'ekun iyonu Olugbala f'omo ti nyagbe orin o kapa inu wo, o lu jedi l'alupa gbogbo abiyamo nyo sese. Ela ri i o roju, Orere ri i o na'gbe bo'ra Eyi npa lemo lo diieso, ore ikoko, kosemani awon abiyamo, eni araiye nijijadu ra. O de ilu Ibo, o doga, o de ile Hausa, o d'oba, gbogbo Onisegun l'o so pe ko legbe, gbogbo omode lo nfe e fun ilera.

IGO KEKERE 2/6d IGO NLA 4s owo oko loto.

THE EGBA TRADING ARADAN STORES

18, Denton Bridge Street
P. O. Box 2 Ebute -Metta






## EGBE ACTION GROUP LO ... GBAJULE



Eniti a nwo aworan re yi ni Oloye Anthony Enahoro on lo so bayi wipe, ohun pataki ti o se ki awon enia fi si eto ki awon to dibo fun enikeni, o ye ki awon ro jinle, iru ise tabi anfani ti iru egbe be ti se ni igbawaju ti o si han gedegbe si enikeni.

Eyi ni ohun ti eto yato ki e to dibo fun egbe Action Group. (1). Action Group ni ti o to gbe oju le ti o si se fi okan te. (2) Egbe yi lo je eniti o lagbara lati da Middle Belt state ati C.O.R. State sile lehin ibo didi. (3) Alafia ara to enikeni ni agbegbe Iwo-Orun nibiti egbe yi gbe nse ijoba.

# LAGOS RACE CLUB

## Christmas Meeting 1959 - 60

SATURDAYS 19th & 26th DEC. 1959. FRIDAY 1st, SATURDAYS 2nd & 9th January, 1960.

| FIRST DAY | | START |
|---|---|---|
| RACE NO. 1 | Six Furlongs Handicap Bottom Division | 2. 30 p.m. |
| RACE NO. 2 | Six Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 00 pm. |
| RACE NO. 3 | Six Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 30 p.m. |
| RACE NO. 4 | Eight Furlongs Handicap Middle "B" Division | 4-00 p.m. |
| RACE NO. 5 | Eight Furlongs Handicap Middle "B" Division | 4. 30 p.m |
| RACE NO. 6 | Eight Furlongs Handicap Middle "B" Division | 5.00 p.m. |
| RACE NO. 7 | Eight Furlongs Handicap Middle "A" Division | 5. 30 pm |
| RACE NO. 8 | Seven Furlongs Handicap Top "B" Division | 6.00 p.m. |
| RACE NO. 9 | Eight Furlongs Handicap Top "A" Division | 6. 30 p.m |

| SECOND DAY | | |
|---|---|---|
| RACE NO. 1 | Nine Furlongs Handicap Bottom Division | 2.45 p.m. |
| RACE NO. 2 | Nine Furlongs Handicap Bottom Division | 3.15 p.m. |
| RACE No. 3 | Six Furlongs Handicap Middle "B" Division | 3.45 p.m. |
| RACE NO. 4 | Six Furlongs Handicap Middle "B" Division | 4.15 p.m. |
| RACE NO. 5 | Six Furlongs Handicap Middle "B" Division | 4.45 p.m. |
| RACE NO. 6 | Six Furlongs Handicap Middle "A" Division | 5.15 p.m. |
| RACE NO. 7 | Five Furlongs Handicap Top "B" Division | 5.45 p.m. |
| RACE NO. 8 | POLO SCURRY | 6 15 p.m |

| THIRD DAY | | |
|---|---|---|
| RACE NO. 1 | Eight Furlongs Handicap Bottom Division | 2. 45 p.m |
| RACE NO. 2 | Eight Furlongs Handicap Bottom Division | 3.15 p.m. |
| RACE NO 3 | Nine Furlongs Handicap Middle "B" Division | 3. 45 p.m |
| RACE NO. 4 | Nine Furlongs Handicap Middle "B" Division | 4. 15 p.m. |
| RACE NO 5 | Nine Furlongs Handicap Middle "B" Division | 4. 45 pm |
| RACE NO. 6 | Six Furlongs Handicap Top "B" Division | 5. 15 p.m |
| RACE NO. 7 | Nine Furlongs Handicap Middle "A" Division | 5.45 p m |
| RACE NO. 8 | Five Furlongs Handicap Top "A" Division | 6 .15 p.m |

| FOURTH DAY | | START |
|---|---|---|
| RACE NO. 1 | Seven Furlongs Handicap Bottom Division | 2.45 pm |
| RACE NO. 2 | Seven Furlongs Handicap Bottom Division | 3.15 pm |
| RACE NO. 3 | Five Furlongs Handicap Middle "B" Division | 3.45 pm |
| RACE NO. 4 | Five Furlongs Handicap Middle "B" Division | 4.15 p.m. |
| RACE NO. 5 | Five Furlongs Handicap Middle "B" Division | 4.45 p.m. |
| RACE NO. 6 | Five Furlongs Handicap Middle "A" Division | 5.15 pm |
| RACE NO. 7 | Eight Furlongs Handicap Top "B" Division | 5.45 pm |
| RACE NO. 8 | Sixteen Furlongs Handicap Top "A" Division | 6.15 pm. |

| FIFTH DAY | | |
|---|---|---|
| RACE NO 1 | Four Furlongs Handicap Bottom Division | 2. 45[illegible]p.m. |
| RACE NO. 2 | Four Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 15 p.m |
| RACE NO. 3 | Four Furlongs Handicap Bottom Division | 3.45 p.m. |
| RACE NO 4 | Seven Furlongs Handicap Middle "B" Division | 4. 15 p.m. |
| RACE NO. 5 | Seven Furlongs Handicap Middle "B" Division | 4. 45 p.m. |
| RACE NO. 6 | Seven Furlongs Handicap Middle "B" Division | 5.15 p.m. |
| RACE NO. 7. | GOVERNOR-GENERAL'S CUP Ten Furlongs | 5. 45 p.m. |
| RACE NO. 8 | Seven Furlongs Handicap Middle "A" Division | 6.15 p.m. |

**gbogbo ẹniti o ri i pe awọn oṣiṣẹ Reluwe ti da ijọgbọn sile lo nsa asala fun emi ara wọn.**

**Nigbati o ṣe ogun awọn ọlopa yo lati ọna Ebutemetta, nwon si ka arọ na mọ arin ohun ti o ya enia lenu ni wipe arọ gbe ese re kuro lorun re o dide duro, o si fi ese fe, o nsare lo gbogbo enia ku si erin. Bayi ni aro na ba salọ bamu-bamu.**

paṣe pe ki nwon da iṣe sile. Ohun ti a gbọ wipe awon oṣiṣe titori re ko igi ati kunmo ni wipe Sir Ralf Emerson ti o je Olotu ibi iṣe Reluwe nfi ọna ẹtan le awon ti o ṣe pataki ti o si wulo larin awon oṣiṣẹ lọ. Nitorina awon ko le ba Ọgbẹni Emerson ṣiṣẹ pọ, ayafi ki o pada lọ si ilu rẹ.

Lojọ Alamisi na ni awọn oṣiṣẹ se aiya gbangba si awon ọlọpa tobe ti nwon yinbon apamolekun si won, iwọn adọta enia lo fi ara ṣeṣe, iye awon ti nwon ri mu to ọgọrun enia.

## Osise Reluwe Se Iwosan Fun Aro Kan

YABA. Okunrin Arọ kan ti o mba Opopo Clifford lọ si Yaba ti o ko ese re mejeji korun o wa nfi ọwọ ra nile.

Gbogbo awọn enia ti o ba pade rẹ loju ọna, lo nkanu fun u, nwọn fun lowo nwọn si nta lọre.

Lojiji oju Opopo Clifford ni Yaba bere si tu yeriyeri gbogbo awọn enia ti o nfi esẹ rinlẹ lo si Yaba berẹ si pada sebin pelu ere sisa

## OṢIṢE RELUWE BA ỌLỌPA WỌYA IJA

EKO. Okiki kan lọjọ Thursday wipe awọn osiṣe Reluwe gba ina jẹ, nwọn binu da iṣe silẹ, nwon ko igi, nwon si ko kumọ ti gbogbo enia ti o kọ lati da iṣe silẹ pẹlu won, tabi awọn ti nwon yo kelekele gba ọna chin wa sibi iṣẹ nigbati ẹgbẹ won, ti


HINDU SANKARA'S
Religious Art Jewelleries



Perfumes, Charms, Mohammedan charms, Amulets, Vedic Prayers, Kawachas. Faithful Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries.

*Enclose 4/- Postal order by Air Mail for Catalogues and Literature.*

HINDU SANKARA, 431 Archway Road, London, N.6, England


Printed & Published by The Union Printing And Publishing Company 28, Kosoko Street P.O. Box 467 Lagos Phone 23370